# ELETI OFE

'A-NJU-WỌN KO ṢE WI LẸJỌ'

VOL XIV NO 940 LAGOS SATURDAY SEPTEMBER 26—SEPTEMBER 30 1964 KOBO MEJI (2D)

ELELETURE

# Alufa Kan Pelu Awon Oloro Wo Ijakadi

EKO— Ni aṣalẹ ọjọ ọsẹ to kọja ni Alufa Oniwasi kan ti nwọn npe ni Ẹlẹlẹturẹ lọ si Isalẹ Eko lati lọ ṣe wasi, ṣugbọn ni ọjọ yi, bakanna ni awọn Oloro nṣe etutu gẹgẹbi aṣẹṣe fun o u ti Ọba Adele keji ti o gbesẹ ninu oṣu ti o kọja lọ yi.

Ni dede agogo mejila oru ni awọn oloro jade sita lati ṣe etutu kakiri igun mẹrẹrin Isalẹ Eko, Alufa yi si wa nita ti o nṣe wasi.

Alufa yi nkewu, o si nṣe Waka orişirişi bayi wipe "Awa yin la l'Eko, Ẹlẹlẹturẹ" awọn oloro papa nkọrin wipe "Ki ọlọgbẹri mu ọgbẹri so, Oro baba o!" bayi ni ija bẹ silẹ larin oniwasi ati awọn oloro.

## Dokita Banda Minisita Malawi Ni Awon Aje Fe Pa On

BLANTYRE — Ko si ibi ti eṣe ko si, Dokita Kamasu Minisita alakoso ilu Malawi ti nwọn ṣẹṣẹ gba ominira Ijọba lọwọ awọn Oyinbo ni aipe yi, ni awọn minisita keekeke ti o wa labẹ on fẹ pa on. O ni nwọn ti nwa awọn babalawo kiri lati gba oogun lọwọ wọn ki nwọn fi pa on.

(Wo yo u lo u e e ẹfa)

## Olopa Ko Awon Jaguda Obinrin

TOKYÔ — Awọn ọlọpa ni ilu Tokyo ti nṣe olu ilu Japan ni a gbọ pe nwọn ti ko obinrin mọkanlelọgbọn ninu awọn enia okoo lerugba o din meje enia (213) ti nwọn nṣe iṣe jaguda ti nwọn ti bẹrẹsi mu lati ọjọ kinni oṣu kẹfa ọdun yi ninu şişe ti jaguda le parẹ bamubamu ki ere ije sisa nla ti nwọn fẹ ṣe ni ilu Tokyo to bẹrẹ ninu osu to mbọ.

## LAGOS RACE CLUB

IPADE ERE ẸŞIN FUN OŞU OCTOBER 1964.

Ere Ẹşin yio bere ni ọjọ wọnyi–
Sunday 4th, 11th, 18th, 25th, October ati 1st November 1964.
Agogo mẹta ọsan ni awọn ẹşin yio bẹrẹsi sa e ije ni awọn ọjọ ti a to soke yi.

### ASỌTẸLẸ

Asọtẹlẹ şiwaju ere ẹşin yio bẹrẹ ni agogo kan abọ si agogo meji ọsan ninu ọfisi akọwe ẹgbẹ ni ọjọ ipade ere ẹşin ni Ọdan l'Eko.

### OWO IWỌLE

Şile mẹta ni owo iwọle ni ọjọ kọkan pẹlu owo iworan.

### AWỌN ỌMỌDE

Awọn Ọmọ ti ọjọ ori wọn ko ba to ọdun mẹrinla ko ni wọ inu ọgba ibiti ẹşin gbe nsare.

### ORIRE

Tita ati pipin owo orire yio wa ni ọjọ kọkan ti nwọn ba şe ipade ere ẹşin, nọmba to wa ninu iwe iwọle onikalu u ni yio fi han bi ẹnikan ba jẹ owo. Ẹnikini yio gba £2:10/-, ẹnikeji yio gba £1:10/- ẹnikẹta yio si gba 10/-.

### ETO ERE ẸŞIN

Ẹ o ri akọyanju eto nipa ere ẹşin fun ọjọ mararun yi ra ni şile mẹrin pere.

# ELETI - OFE

(A NJU WON KO SE WI LEJO)

EDITORIAL OFFICE & WORKS CABLE & TELEGRAMME
28, Kosoko Street; Lagos, "ELETI-OFE" LAGOS
P.O. B.x 467  Phone 23370

VOL. XIV. NO 940  SATURDAY Sept. 26—Sept. 30 1964


# Iwe Si Olotu

pe'u onitie loja re to nsun bi om odo, O ni; "Dariji mi ki em le ni anfani lati tun aiye mi se eyiti mo ti fi Segbe sihin Obinrin na kan ni bi adajo baje nikehin adajo ni; ki o lo san po un mewa tabi ki o lo sewon osu kan ti k o b a rowo san

# Elewon Kan Tori Iyawo Re Sa Kuro L'ewon

OTURKPO—Ko si iru nkan ti oro obinrin ko le fi oju okunrin ri, nitori tipe oro obinrin dun elomiran l okan ju ti ara won lo, iru nkan yi ni a gbo laipe yi nipa ti elewon kan to sa kuro logba ewon ilu Oturkpo pelu aso ewon ti o si di ranse pada si oga awon elewon gegebi eru kekere ti nwon fi nransé ti ilu okere wa, sugbon owo olopa ti tee, o si ti pada sewon.

Ojo Ameh, eni odun mokandinlogoji ni o si lu ro lewon da ... awon ti nwon wa ninu kotu ni gbati o sofun adajo pe ... tori ki on ba le lo ri ... Iyawo on nile ni on se sa kuro lewon, sugbon lati e je ki oga awon elewon mo ey daju, on ba di aso ewon ara on ranse pada si, ko le toju re fun on.

Gbogbo alaye to se ko jamo nkankan niwaju ada jo, o ba so sewon odun kan pelu ise asekara ati bulala mefa to gbona nini re.

... ti adajo ti da ewon fun Ameh tan odaran na ... wa sofun adajo pe on yio dejo kotemilorun lori dajo yi, nitoripe adajo ti kuna lati fi ... ro nipa ero ... ti ni lokan nipa lili aso ewon on ranse pada si woda ki o to tun wa pada sogba ewon

# Adajo Ni Oyenuga Jare Ejo Unifasiti

IBADAN — Oro ejo kan ti ojogbon ninu iwe ati olukoni, Dokita V.A. Oyenuga pe awon a'akoso ile-iwe giga Unifasiti ti Ife lori didaa duro lenu ise lainidi ati lona ti ko to, ti de opin ni Ojo Isegun to koja ni Ibadan, nigbati Adajo agba , Ogbeni Adegboyega Ademola n awon Kansulu to je alabojuto ile iwe yi ko ni eto lati da omowe Oyenuga ati awon elegbe re ti nwon je oluko ninu ile eko giga Unifasiti Ile Ife, awon na ni

(Wo iyoku loju ewe karun

# Vrufin Obinrin Kan Be Adajo K'o Dariji On

SHAGAMU—Ni Ojo Aje to koja, obinrin alagba kan ti awon olopa nba sejo ninu kotu adajo towa ni Shagamu be adajo re ki o dariji on pelu ikunle, lehin ... ti ... "Mo ti ronu piwada lori gbogbo asise mi to ti koja, mo si ti mu ona igbesi aiye ti un lati wa yato le"

Eniti o soro yi ni obinrin ... oruko re n se Folake Joseph ti awon olopa nba sejo ... fi iwosi ... fun ... okunrin telo kan to be ge ... pa telo na lori ... ibi kan ... awon ... ni opopo ... kun ni Shagamu ni ojo ke rindinlogbon osu kefa odun yi.

Gegebi oro ti awon olopa so nwon ni Folake fi igo ati bireki lu telo niwaju eniti oruko re nje Moses Adesanya, nigbati telo ni ki Folake fi ... ise on sile lati fi ye sile fun awon onibara on.

Folake se kunle o si so pe on ko jebi rara o wa ... adajo pe ki o saun on


BP PASS ALL! · BP PASS ALL! · BP PASS ALL! · BP PASS ALL!

Fun ina dídá ati fun imole

BP SUPERLITE

KEROSINE

L'ayo!




Ti o ba sepe Kerosine lo fe BP Superlite l'ayo o le ri ra nibikibi, ko si won, o mó daradara, owun lo si dara ju fun onje-sise, ina-titan ati lati mu fi yana Kerosine ti o dara to BP Superlite

BP

ju gbogbo won lo!

BP PASS ALL! · BP PASS ALL! · BP PASS ALL! · BP PASS ALL!

# Awon Ibo Gbogun Ti Olopa Ni Aba

ABẸOKUTA—Awọn ara-ku r n ọmọ iya meji kan, Al mi Ad sa, ọmọ ọdu i mejila ati Tịamiyu Akann ọmọ ọdun meje nị a gbọ ri ọjọ Ẹti to kọj wi e ina jo pa inu ina nla kan to jo nị kutukutu owurọ ni abule kan tị oruko rẹ njẹ Ajao ni ọna Abẹokuta.

Ọlan ninu awọn mejeji to jẹ ọmọ ile iwe to wa lo isimi ni abule wọn pẹlu ekejị rẹ wa loju orun lọwọ nigbati ina na bẹrẹsi jo to si gbe wọn mi, ile meta ni o si segbe ninu ewu ina na eyiti iye owo na je ọdunrun ponun (£300. Ẹnịkan ti okan y ṣ ju rẹ nị ina gbinaya nigbatị atupa fitịla ti nwọn gbe si ara ogiri ile ran mọ ole ninu awọn apa aja ileu yara nigbana ni obi awọn ọmọ na Ọgbẹnị Yenusa ati Iya fin Ajọkẹ wa fi gbe ta, latị inu iyara mịran nịb ti nwọn gbe sun si.

Gbogbo awọn ara abule ati ịbatan wọn ni nwọn sa ipa wọn lati gbẹmị awọn ọmọ mejeji yi la, tobe ti awọn alara fẹrẹ bọ sinu ina ọla na.

Nikẹhin, ogun'ọgọjị awọn ara abule na t nwọn ja fitafita nigbati ina na njo ri ẹhin ina yi lẹhịn ọpọlọpọ iṣẹ aṣelaịun won sị t gbe oku awọn ọmọ na ti ina ti yan lọ si ile awọn lakulaku.

## Ina Jo Omo Iya Meji Pa Ni Arin Ilu

ABA — Ija nla kan bẹ silẹ nị ọjọ Abamẹta to koja larin awọn ara abule kan ti nwọn npe ni Egbe u ati ati awọn ọlọpa agbowori ti Kansulu ilu Ndok ni agbegbe Aba, nigbatị nwọn lọ gba owori nibẹ.

A gbọ pe enia mẹrin ninu awọn agbowori na ni nwọn gbọgbẹ ninu ija nla na beri nwọn si ti fi igi Olugboro, okuta ati ada ba ara wọn ja lathikita, ṣugbọn nisisịyi meje ninu awọn ara abule na ni awọn ọlọpa ti ko lọ ti mọle nị ogba wọn to wa ni Afam fun ịbere ọrọ lori ija to ṣẹlẹ.

Fịfi aake kori lati san owo ori ati lati tẹle awọn ọlọpa de ọgba wọn nịgbati nwọn mu wọn ni o da ija silẹ. Ọn we ịrohin nị Aba sọ wpe ni oṣu kẹfa ọdun yị, awọn ara abule yi ti pinnu lati faake kọri n pa ssan owo orị ati ti om fun awọn Kansulu na ni ọdun yi nitorịpe nọ ti ya awọn ṣọtọ gẹgẹbi ilẹbapinnu nu anfanị (Woyoku loju ewe karun)

# Iwe Ti Tarka Folo-pa Ko Waiye

GBOKO — Irohin kan it o ti n a nilẹ fun bi ọjọ meo kan nipa iwe ti nwọn ni Ọgbẹni J.S Tarka to ṣe asiwaju ẹgbẹ UMBC gle fun ayẹwo awọn ọl pa ninu yiti o ni eto ti wa nilẹ lati di ihamọra ohun ila la o o bo to nbọ yi ti o o fi ranṣẹ si Ọgbẹni L. O Edet ọjọ ni kẹrin oṣu yi, ni a gbọ wipe awọn ọlọpa ti ṣe ayẹwo rẹ, nwọn si sọ pe nwọn ṣe eru nipa iwe na ni.

Ohun to mu ki awọn ọlọpa ṣe ofintoto iwe adamọde yi ni nipa aṣẹ kan ti Ọgbẹni Ener ni ki nwọn ṣe nigbati o ri iwe na gba, a tun gbọ wipe ninu kotu adajọ kekere to wa ni Gboko, adajọ ni ki ọkunrin kan ti awọn ọlọpa mu to si tun jẹwọ pe on ni o ṣe eru ati adamọde iwe yi lọwọ ara on lọ fi ọgbọn ponun tanrafi.

Adajọ ni ọdaran na jẹbi gẹgẹbi itọsẹ ofin ijọba ti ipinlẹ Ariwa a p a iriuwo din meje (Section 393) to mu enia to ba ṣe nkan to le mu abuku tabi ipanilara lọna ti ko dara dani.

Ọgbẹni Tarka papa ni o kọkọ ṣe ifiiọ tabi ikede iwe adamọde ọlọtẹ yi ni kete ti o kọ ọ ri uibi ipade kan to ṣe pelu awọn oniwe irohin lọsẹ to gbẹẹin ninu oṣu to kọja o si sọ pe on ti fi ẹda iwe na ranṣẹ si ọga awọn ọlọpa.

Lẹhin ti iwe na ti tẹ ọga awọn ọlọpa lọwọ tan ni nwọn ba ranṣẹ pe Tarka fun ibere ọrọ ni ile iṣẹ won ni Eko, oru ọ Tarka ni nwọn kọ sinu iwe na ọjọ ti nwọn kọ iwe na gẹgbi ọjọ kẹta oṣu September, 1964.


# Eleti-Ofe D'araba



**E ma polowo oja yin, ki e si tun ma ka iwe irohin**

**ELETI–OFE**

**ti o kun fun irohin aladun losose.**




# Odaran Kan Subu Ninu Apoti Ejo Ni Kotu

ABA — Ọdaran dẹrẹba kan ti orukọ rẹ njẹ Michael Onyekwere ni a gbọ wipe oyi kọ lu to si ṣubu lulẹ ninu kotu adajọ awọn ọlọpa ni Aba nigbati o njẹjọ lọwọ ni Ọjọ Abameta to kọja.

Ẹsun ti awọn ọlọpa mu Onyekwere fun ni wiwa moto lọna to lewu ati fifi moto pa enia lailẹtọ, bi ọlọpa to mu ọdaran yi si ti fẹ bẹrẹsi ma ka ọrọ to fi ọwọ ara rẹ kọ si adajọ leti, bẹni oyi gbe ṣanlẹ.

Lẹhin ti Dọkita R. S. Garach eniti o wa ninu kotu lakoko ti oyi gbe ọdaran na ṣanlẹ ti ṣe ayẹwo rẹ tan, lẹsẹ anna ni nwọn ba gbe lọ si ile-iwosan, adajọ, Ọgbẹni A. Onyechi si fi atungbọ ẹjọ na si ọjọ kẹsan oṣu kẹwa ọdun yi.

Siwaju awọn ọlọpa ṣe alaye fun adajọ wipe ni ọjọ kẹrindinlọgbọn oṣu karun ọdun yi, Onyekwerọ wa moto rẹ to fi nṣe takisi lọna to lewu, o si fi nse moto akẹru kan to duro leba ọna Aba si Owerri, ọkunrin kan ti orukọ rẹ njẹ Joel Nwoke, ọkan ninu awọn ero to wa ninu moto ba ku bamubamu.

# Olosa Sa Omolewepa

ILE-IFẸ-Ni owurọ ọjọ kẹwa oṣu to kọja ọmọbinrin ọmọ'ewe kan fi ile rẹ silẹ lati lọ si ile-iwe rẹ to wa ni agbegbe ile wọn nitosi abule kan ti nwọn npe ni Wanikin ni eti Ifẹ, ṣugbọn danadana da lọna nigbati ko fi nkan ti ọdaran na nfẹ fun.

Oro ọgbẹ ada ti o wa lara rẹ pọ tobẹ ti ọmọbinrin na fi nke rora iẹba ọna ṣugbọn ko pẹ n a ni onirure kan ba yọ o si ṣe iranlọwọ lati gbe lọ si ile awọn alaisan nibiti nwọn gbe wo san, a gbọ wipe danadana na ti orukọ rẹ njẹ Oladipọ Adumadajin ti salọ wọn ko si ri mọ ti di ọjọ keji.

Nigbati awọn ọlọpa mu Oladipọ de iwaju adajọ kotu kekere ni Ile-Ifẹ ni Ọjọ Iṣegun to kọja ọmọbinrin ile iwe eniti orukọ rẹ njẹ Mercy Gabriel ni nigbati on nlọ loju ọna Oladipọ ni ki o nba on kalọ sinu oko, ṣugbọn nigbati nwọn de inu oko, o sofun on lati yọdi ṣehin, on si ko lati ṣe bẹ.

Lori kiko yi, ko ṣopo sẹ meji, o ba fa ada rẹ yọ lakọ o si ṣa on tibinu tibinu Nigbati Oladipọ ma wi o se kanle patapata, adajọ si kọ ọrọ rẹ o ni irọ ni o npa o ba sọ sẹ on ọdun meji pẹlu iṣẹ aṣekara ati bilala mejila ni idi rẹ.

# E ka oro

## Awon Ibo Gbogun Ti Olopa

(loju ewe 1 e a)




# Okunrin Kan Pa Omo Meji

MUSHIN— Gẹgẹbi irohin kan ti a gbọ lori hilahilo kan to ṣẹlẹ ni No 46, Opopo Martin ni ni Mushin ni ale ọjọ kẹtadinlogun oṣu yi nibiti okunrin kan gbe fi ake ṣa ọmọdekunrin ati ọmọdebinrin kan pa, a gbọ pe awọn ọlọpa ti mu ọkunrin na lọ siwaju adajọ awọn ọlọpa ni Ikẹja fun ẹsun ipania.

Lẹhin iṣẹlẹ buruku yi, awọn ọlọpa ba gbe oku awọn ọmọ mejeji Mu- bau Ajọsẹ ọmọ oṣu mejila pere ati Samuel Isaac, ọmọ ọdun marun abọ lọ si ile awọn lakulaku, ati pe Iyaafin Fadilatu Ajọsẹ to jẹ iya Muyibatu farapa o si wa nile iwosan pẹlu irora nla ni Eko.

Eniti o ṣiṣẹ buruku yi ni Agwu Imagba eni ego ji ọdun to nṣeṣẹ onṣegun babalawo. Iyaafin Elina Isac to jẹ iya to bi Samuel, enitị ọkan rẹ kun fun ibanujẹ ni ọmọ kanṣoṣo ti on ni nwọn ti pa mọ on lọwọ.

Iyaafin Elina pẹlu omije loju ni bale on ti lọ si irin ajo si ilu awọn Ibo, bẹni on ko si mọ nu ohun ti on le sọ fun ti o ba de nipa ọmọ na, awọn ebi, ibatan ati ọrẹ ni nwọn joko ti, nwọn si nba kẹdun pẹlu ọrọ itunu.

**Akiyesi Ka oro ti Olola Azikiwe so lori oro ti Ogbeni Ogedengbe so loju ewe karun.**

## Awon Ibo Gbogun ti Olopa Ni Aba

(O bere loju ewe keta)

ABA — ti n won se fun awon ilu to kuś

Awọn ara abule na n i lori gbogbo aroye ti a on ko lọ ba kansulu n pa il sẹh n to wa nilu wọn, sibẹ na nwọn fi gbigbo se alaigbọ.

Ọgbẹni S vester Nwekc to jẹ alaga fun Kansulu na ni ru iwa t awọn ara abule na hu ki iṣe ohun to boju m , b n, ko si b! wọn ti le ṣe o a su u y o gba owo na lọwọ wọn dandan.

O tun ni k n ọ ebe ọrọ to ba ndun wọn lọkan lọ sọdọ awọn kansulu on ni ọna ti o to, ki iṣe ru ọna bayi ni nwọn le fi ri ibere wọ gba

## Olola Meji Wewon Ni Makurdi

Awọn okunrin meji kan ti nwọn Ṣapejuwe gegebi ọlọla alejo ti nwọn gba agbawọ ninu ile isimi t awon ijoba lọ fun awọn alejo ni ilu Markurdi ni adajo kotu (Grade B) ti paṣẹ pe ki enikọkan wọn lọ sẹwọn ọdun mẹta nitoripe nwọn ji redio kan ati apoti aṣọ ti nṣe ti Ọgbẹni John Walton Fuller, apapọ o o eyiti o jẹ ọgọsan ponun (£180)

Oru ọ awọn d a na Ogonna Oha ati Ashwe Am m t awọn ọpa ni a ọ woso ati ara gẹgẹbi ọlọla ati e a pataki ti nwọn si gba agbawọ ninu ile isimi ti ijọba kọ ni Makurdi nibi ti nwọn gbe fọ ilẹkun enu ọna yara Ọgbẹni Fuller pẹlu ọgbọn ole ti nwọn si gbe redio ati apoti aṣọ rẹ ni ọjọ keji la iṣa yi.

Nikẹhin awọn ọlọpa ba te wọn ninu ile ọti kan ni Makurdi. Ninu idajọ ti adajọ Malam Garuba Sarkin Taraku ṣe le wọn lori, o ṣe apejuwe awọn mejeji gẹgẹbi enu ọlọgbọn jomba, ati wipe on ko ni jafara lati ma fi ekun rere iya je enikeni ti nwọn ba mu wa siwaju on fun iru esun bayi.

Malam Garuba n ki awọn ọlọpa tanbọ ẹpa mọṣe lọjọ iwaju bi o ti jẹ pe awọn ẹgbẹ ọlọṣa nghidanwo lati fi Makurdi ṣe ibubi wọn

## Azikwe Ni: Mase Lo Oruko Mi Lona Odi

NSUKKA — Ọ ọ kan ti Ọgbẹni Ogede g e Mac la so ninu ipade awọn ọdọmọde ọmọ ẹgbẹ Demo p gbogbo awọn ọmọ ẹgbẹ n pẹlu awọn ọm ẹgbẹ O (NPC) ti fohun ṣọkan lati fi Ọlọla Adesoyinbo Ademola, olori awọn adajọ jẹ b lẹ ala oso Ijọba Apapọ ṣe bi ẹgbẹ awọn ba bori idibo ti awọn fẹ di yi, ti d ọrọ ti Dokita Azikiwe fọnmu si.

Dokita Azikiwe ni k awọn enikan mọ ori gba ti Ọlọla Ademola nitoripe ọrẹ ni on pẹlu rẹ O ni on mọ wipe ọpọlọpọ awọn ọmọ ẹgbẹ oṣelu ni nwọn ti nmura idibo silẹ, on si mọ wipe ko si nkan ti o wọn lẹnu lati sọ ki nwọn ba le ri enia aburata lati dibo fun wọn.

Dokita Azikiwe ni ara on ti ko ya ni o jẹ ki on fara s Nsu fun ọjọ ti wipe on ti fẹ lọ si ilu Oyinbo lati lọ ri awọn dokita ibẹ fun ayẹwo ara on ṣugbọn on o fẹ fi ile silẹ nitori awọn nkan ti o nṣẹ nile lati enu ọjọ mẹta si leralera, o ni on si i eyi fun Ọlọla Tafawa Balewa lati fọkan rẹ balẹ wipe on a dara duro.

## Adajo ni Oyenuga Jare Ejo Unifasiti

(o bere loju ewe keji)

Dokita S.A. Aluko, Dokita I.O. Odumosu, Dokita A. Fayẹmi ati Ọgbẹni M.A. George tiṣe ọga ilẹ itọju

Adajọ paṣẹ pe ke nwọn lọ san ọdunrun le egbed gbọnj ponun o din ponun mẹfa, ṣile mẹta ati kobọ n (£5,294:3:1d) fun ọmọwe Oyenuga ati awọn e yoku. ṣugbọn awọn Kansulu Unifasiti Ifẹ pe ejo ko milọrun lati san owo yi, sibọ na adajọ faake wọn o tun ni ki nwọn lọ san ponun mẹwa ati ṣile mẹwa f owo irinsẹ.

(Wo yoku loju ewe kẹfa)


# Eleti-Ofe D'araba

**E ma polowo oja yin, ki e si tun ma ka iwe irohin**

**ELETI–OFE**

**ti o kun fun irohin aladun losose.**





# Adajọ Ni Oyenuga Jare Ejọ Unifasiti

(O bẹrẹ loju ewe keji)

Iye owo ti Dokita Oyenuga ati awọn mẹrin to ku fẹ gba lọwọ awọn alaṣẹ Unifasiti na ju ẹgbẹdọgbọn pọnun lọ, (£5,000) gẹgẹbi owo oṣu wọn lori dida wọn duro lẹnu iṣẹ, ati pe Oloye A. M. A. Akinloye to jẹ lọya fun Unifasiti ti sọ ṣaju fun adajọ pe on faramọ ibere ti awọn Dokita Aluko, Fayẹmi, Odumosu ati ti Ọgbẹni George ṣi gbọn on kọ ti Dokita Oyenuga.

Ninu afikun ọrọ ti Ọgbẹni R. O. A. Akinjide to tun jẹ ọya fun Unifasiti na ṣe ninu iwe ipẹjọ, o fi ye adajọ pe lori iwa bubburu ni nwọn ṣe da Omọwe Oyenuga duro. Lẹhinna nwọn si ti san owo oṣu rẹ fun oṣu mẹfa fun gẹgẹbi ẹbun.

Ọgbọn iṣẹju ni adajọ fi ka idajọ rẹ ne, o ri ki awọn Kansulu Olupese fun Unifasiti Ifẹ lọ san owo ti on pa laṣẹ fun wọn. pẹlu pọnun meji'oladọta ati ṣi e awẹwa gẹgẹbi owo irinṣẹ fun awọn marun rilo are ti nwọn jẹ ninu ẹjọ ajumọpe wọn na adajọ tun wa bere lọwọ Oloye Akinloye pe o ṣe gba ẹjọ ti awọn mẹrin ti o si da ti ọiọgbọn Oyenuga ya sọtọ a gbati o jẹ pe nwọn jumọ pẹjọ ni.

Lẹhin eyi Oloye Akinloye ni gẹgebi eto igbaniṣiṣe lori eyiti Dokita Oyenuga fi nṣẹ tẹlẹ ri ni Unifasiti o ṣilati wa ninu iṣẹ yi n gbogbo igba aiye rẹ titi yio fi pe ẹni ọgọta ọdun.

Ni ipari ọrọ, adajọ Ademọla ni on gba daju re ọna ti ko lẹtọ ni nwọn fi da Oyenuga duro lẹnu iṣẹ ti a on mẹrin to ku pẹlu nipa bayi ẹtọ wa fun wọn lori owo ti nwọn fẹ gba gẹgẹbi iwe ipẹjọ wọn.

## Ijoba Kano Pa Waasi Sise Larin Ita Re

KANO—Irohin kan de si ile wa lati ilu Kano ni ipinlẹ Ariwa ni ọjọ Iṣẹgun to koja wipe awọn ẹgbẹ Onimale ti ilẹ Naijiria ti ile Ariwa ni awọn faramọ ofin kan ti ijọba ilu Kano ṣe nipa ṣiṣe Wasi, ati kika Korani larin titi ni igboro ilu Kano eyiti awọn ti nwọn pe ara wọn ni Mallam tabi Alufa ma nsaba ṣe.

Ninu iwe kan ti akọwe ẹgbẹ yi, Alhaji Hashimu Magoga ni Kano tẹ jade, o ni ru ofin ti ijọba ṣe yi jẹ eyiti o ba asiko mu bi o ti jẹ pe enia mọ daju wipe kaka ki iṣẹ awọn Mallam wọnyi jasi rere, ibi ni o jasi, nipa ẹsin Imale nipa aigunrege ati Wasi ti awọn ma nṣe kakiri titi, ati titumọ Kora ni laiyanju to nitori imọ a ijinlẹ ti nwọn ni lori ẹkọ Alukurani ati eto ẹsin Imale.

Awọn ẹgbẹ Onimale na tun sọ siwaju pe awọn adamọde Mallam wọnyi fẹran iwa kan lati ma wẹ ẹnu ebu si awọn alaiṣẹ lara, wọn a si ma fẹ fi bi nwọn ti to kan wọn pẹlu didibọn pe aṣẹ to ti ẹnu Olorun jade ni.

Nitori eyi awọn ti ke igbe ẹbẹ si gbogbo awọn ijọba ibilẹ ni gbogbo ipinlẹ Ariwa papa julọ ninu awọn agbegbe to jẹ pe ekida awọn Imale ni n ọn ngbe ibẹ lati tẹ'e iru aṣẹ rẹ ti ijọba ibilẹ Kano ṣe, lati le mu ki awẹmọ ati iyi ti ẹsin Imale ni le wa ni om nira ati gigun rege ati nkan ti a le gbala kuro lọwọ awọn Mallam alailẹye wọnyi.

# Ile Gogoro



Aworan yi niti ile gogoro ni ilu Oyinbo

## Dokita Banda Minisita Malawi

(O bẹrẹ loju ewe kinni)

Nigbati minisita alakoso Ijọba Malawi yi mba awọn ara ilu rẹ sọ'ọ ni ilu kan ti nwọn npe ni Ngabu ninu ọsẹ yi ni o bẹrẹsi tu aṣiri yi:

A gbọ wipe awọn mẹfa ninu awọn minisita alabaṣiṣe ti nwọn wa ninu iṣẹ Ijọba ilu na ni nwọn binu kọ iṣẹ silẹ fun ninu oṣu yi Dokita Banda ni ninu awọn Minisita na ni nwọn ran awọn obinrin lọ sọdọ iya-ajẹ kan ninu igbo wipe ki nwọn ba awọn wa oogun ti awọn le fi bọ on lọ ọ ti o le pa on lesẹkẹsẹ O ni iya-ajẹ na kọ jalẹ wipe on ko le ala ilu awọn.

Dokita Banda ni awọn enia ibi na tun lọ si ile'o kan ti baba onṣegun kan wa, awọn ni ki o ba awọn wa oogun lati pa on ṣe sugbọn iyen tun kọ jalẹ.

O ni ko si ẹsẹ ti on fi se awọn ti nwọn fẹ pa on yi ju wipe kikọ ti on kọ lati ko awọn eniaddudu si ipo Oyinbo nitoripe awọn ṣẹṣẹ bere Ijọba ṣiṣe ni awọn ko ti ri enia ti o mọ iṣẹ ọga iṣẹ to larin awọn enia on na

## Iyawo Baie Olympio D'ologbe Ni Dahomey

TOGO—Agbọ irohin wipe Iyaafin Olympio, iyawo Babe ilu Togo, ọgbẹni Sylvanus Olympio ti nwọn pa nipa oro ninu ọdun to kọja ti dologbe ni ilu DAHOMEY laipe yi:

Ọgbẹni Nicholas Grunitzky ti nṣe Bale ilu Togo nisisiyi ni o ṣe ikede na ni Lome nipa iku Iyaafin Olympio to ṣẹle ni Dahomey, ni ilu awọn Kurumọ

Bale Olympio ti o kọkọ dologbe ni a gbọ pe awọn kan ti nwọn doju ijọba rẹ bolẹ ti nwọn si gba ijọba lọwọ pa ni ipa oro ni ọdun to kọja

Printed and Published by The Union Printing and Publishing Company, 28, Kosoko Street, Lagos Phone 23320; Editor, (Olotu) Ọla Ọnatade 15, Kosọkọ Street, Lagos, P O 467, Lagos,